MAṢE BẸRU IKU

Jesu wi fun u pe, Emi ni ajinde, ati iye: eniti o ba gba mi gbo, bi o tile ti ku, yio si yè: enikeni ti o ba mbe laye, ti o si gba mi gbo, ki yio ku lailai...
Johannu 11:25-26

Ṣọ adura yii si Ọlọrun ni igbagbọ:
Jesu Oluwa, o se pupo fun ife nla re fun mi. Mo jewo elese ni mi mo si toro idariji. O ṣeun fun ku lori agbelebu lati san ijiya fun awọn ẹṣẹ mi. Mo gbagbo ninu ajinde re ninu oku. Lati isisiyi lo, mo gbekele o gegebi Oluwa ati Olugbala mi. Mo gba ebun iye ainipekun re mo si jowo aye mi fun o. Ràn mí lọ́wọ́ láti pa òfin rẹ mọ́, kí n sì jẹ́ dídùn inú rẹ. AMIN.

Eyi si ni ifẹ ẹniti o rán mi, pe ẹnikẹni ti o ba ri Ọmọ, ti o ba si gbà a gbọ́, ki o le ni iye ainipẹkun: Emi o si jí i dide nikẹhin ọjọ.
JOH 6:40
Ẹniti o ti gbà wa lọwọ agbara òkunkun, ti o si ti mu wa lọ si ijọba ayanfẹ Ọmọ rẹ̀: Ninu ẹniti awa ti ni idande nipa ẹjẹ rẹ̀, idariji ẹ̀ṣẹ̀:
Kol 1: 13-14 .
Nítorí náà bí ẹnikẹ́ni bá wà ninu Kristi, ó di ẹ̀dá titun: àwọn ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kiyesi i, ohun gbogbo ti di titun. kiyesi i, ohun gbogbo ti di titun. II. KỌRỌ̀ 5:17
Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi aṣẹ fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn ti o gbagbọ́ li orukọ rẹ̀: JOH 1:12

Ṣiṣe awọn iṣẹ rere kii ṣe ọna si igbala, ṣugbọn ẹri igbala wa.

AWỌN OTITỌ MẸRIN WA TI A NILO LATI LOYE NI KIKUN:

1 OLORUN FERAN RE.

Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ́ ge, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun. JOH 3:16
Olè ki iwá bikoṣe lati jale, ati lati pa, ati lati parun: emi wá ki nwọn le ni iye, ani ki nwọn le ni i lọpọlọpọ. JOH 10:10

2 ENIYAN JẸ ẸLẸṢẸ NIPA ẸDA. NITORINA O YẸPA KURO LODO OLORUN.

Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun; ROM 3:23
Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ́; ṣugbọn ẹbun ọfẹ Ọlọrun ni iye ti kò nipẹkun, nipa Kristi Jesu Oluwa wa. ROM 6:23
Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̀kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ: HEB 9:27
Ṣugbọn awọn ojo, ati alaigbagbọ́, ati ẹni irira, ati apania, ati àgbèrè, ati oṣó, ati abọriṣa, ati awọn eke gbogbo, ni yio ní ipa tiwọn ninu adagun ti nfi ina ati sulfuru jó: eyi ti iṣe ikú keji. IFI 21:8

Jesu wí fun u pe, Emi li ọna, ati otitọ, ati iye: kò si enikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipase mi.
JOH 14:6
Nitoriti Kristi pelu jiya lẹ̀kan nitori ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ fun awọn alaisõtọ, ki o le mu wa de ọdọ Ọlọrun, enití a pa ninu ara, ṣugbọn ti a sọ di ãye ninu emí: I. PET 3:18
Ẹnití o ba gbà Ọmọ gbọ́, o ni iye ainipẹkun: enití kò ba si gbà Ọmọ gbọ́, ki yio ri iye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ̀. JOH 3:36

4 A GBODO FI IGBAGBO SI OLUWA JESU KRISTI FUN IGBALA WA.

Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini ki iṣe ti enyin tikaranyin: ẹbun Ọlọrun ni: Ki iṣe nipa iṣẹ́, ki enikẹni má bã ṣogo. EFE 2:8-9

3 JESU KRISTI NI ONA KAN SOSO SI ORUN.

Jesu wí fun u pe, Emi li ọna, ati otitọ, ati iye: kò si enikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipase mi.
JOH 14:6

TI ENIYAN BA YAPA KURO LODO OLORUN NITORI ẸṢẸ RẸ, KINI OJUTU SI ỊṢORO YII? NIGBAGBOGBO A MA RONU AWỌN WỌNYI BI AWỌN OJUTU: ẸSIN, ỊṢẸ RERE, IWA BI O TI WU KI O RI, OJUUTU KANṢOṢO NI OLORUN PESE.